The Chief Secretary to the Govt

Ọrọ Iwe Ipingun Ọgbẹni W. R. Harding Ologbe mbẹ ninu Eko Akete t'oni.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 269. SATURDAY, APRIL 7, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

12 APR 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Jakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


A. Dent

"AWA O MA JO, AWA O MA YQ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

---

**Are you a Mechanic?**—If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house?**— Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o ti lẹ di awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ri nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gba l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kasa.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Abiri Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọja ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremerejibẹ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ẸJẸ ỌMỌ A-ŞAN RẸRẸ BI AGBARA.

Irọkẹkẹ kekere ko ni a gbọ pe o wa ni ita Akanni lẹnu ọsẹ to kọja nigbati a gbe ọkọnrin kan ti awọn kan şa yanayana lọ si Ile Alarun ti Enia Dudu lẹba ọdan, a gbọ pe gişa ti nwọn şa ọkọnrin na pọ gidigidi, ohun ti o si mu sababi yi wa ni ti ọpa-alaiye ti ogun ko şe ogun gẹgẹbi a ti gbọ ọrọ na si, awọn Dokita şe ọlọjọjọ ọkọnrin alaisan yi; o şi wa ni Ile Alarun titi yio fi ri alafia lati ba ẹniti o şa bayi ro'jọ. A gbọ pe awọn Ọpa Ọba ti mu ẹniti o "gişẹ" yi.

## AWỌN OYINBO ỌLỌKỌ ILẸ

(*THE NIGERIAN RAILWAY*)

APA KEJI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji,

Ni aseko ọdun oyinbo eyiti nwọn npe ni Keresimesi (*Christmas*) awọn oyinbo ọlọkọ-ilẹ (*The Nigerian Railway*) nba awọn oşişẹ wọn ti o nşişẹ ni ọko ti şe nlọ ni Iddo ni aye ọjọ kan tabi idaji ọjọ lati şe isimi ọdun ẹwẹ ti o ba si di ni ọjọ ọsẹ *Sunday* ti ọkọ Abẹokuta ti nrin ba ti fi Iddo silẹ, awọn oşişẹ ni Kiriyo ati Imale nwa si ile lati simi, a le pe işẹ ọjọ Sunday ni idaji ọjọ, ti awọn Railway ba mọ ni pataki pe ọjọ ọdun oyinbo Christmas yẹ lati simi tabi lati fun awọn oşişẹ ni aye odidi ọjọ kan tabi abọ ọjọ kilose ti nwọn ki i fun awọn Imale abẹ won ni Iddo ni aye gẹgẹ bi isimi lati şe ọdun ni ile? Bi o ti wa ni liki bẹ lo mbẹ ni gbanja bi ọdun ti wa fun Kiriyo ati Imale bẹ li o wa fun oyinbo ati enia dudu bẹ lo mbẹ fun awọn Musuluni ti a nsọrọ wọn.

Ẹniti o mbẹ ninu işẹ ti ọjọ ọdun ba de, o yẹ ki a ni aye ni bi işẹ na fun ọjọ kan ti ọdun lati fi ọpẹ fun Ọlọrun fun ewu odidi oşupa mejila tabi *twelve calendar months* eyiti o jẹ ọdun kan ti o la kọja, ni iwọn igbati o jẹ wipe ki işe ọjọ Jimọh, oşoşu tabi ni oşu mẹta-mẹta, ni nwọn nşe ọdun eyi ko wọ ararẹ o yẹ ki a fi si ero. kini ero ti a si nfẹ ki awọn oyinbo ọlọkọ-ilẹ şe nipa ọran yi ni wipe ki nwọn maşe ro gẹgẹbi işẹ ti ma lọ si, ki nwọn ro wipe bi awọn oyinbo ti ni ọdun tirẹ ti nwọn nşe laseko *Christmas, New Year* ati ni aseko *Easter* tabi *Good-Friday*, bẹni awọn Musuluni tikalarawọn ni ti wọn, Ekini Eidil, Fitr odun wọn kekere ati Eidl Azhah odun wọn nla tabi *BairamFestval*, odun ko ju ọdun lọ.

Nitoto işẹ pọ fun awọn oyinbo ọlọkọ-ilẹ, bi afo ẹnikan şoşo ba si yọ silẹ lojọ kan a jẹ wipe enia meji lo ni lati şişẹ ẹnikan şugbọn a ko ni lati wo bẹ ni ọna ẹtọ ati gẹgẹbi a ti fi itara sọrọ nipa awọn Musuluni ti a gbo wipe nwọn ko ni aye lati şe odun ni ile, o yẹ wipe ki a mọ wipe Ọlọrun kan na ni oyinbo pelu enia dudu, Kiriyo ati Imale nsin.

O yẹ wipe ki a wo wipe ti a ba fun ẹnikan ni aye (*leave*) ni Ofisi tabi ni Station ko ni ki a ma şe san owo-osu (*salary*) rẹ fun ti nwọn ba ti gbe iwe-ẹri (*voulsher*) jade ti olukuluku ba si ti nfi ọwọ rẹ si, yala, o nbẹ ni ile tabi ni ibi işẹ, ni iwọn igbati nwọn ko da oluwarẹ duro lẹnu işẹ rẹ.

Awa ki işe ọga tabi alabojuto awọn oyinbo ọlọkọ-ilẹ debi ti a le sọ wipe tulasi nwọn o jẹ ki awọn Musuluni bẹre si gba aye ninu ọdun wọn gẹgẹbi atẹhin wa lori ọrọ yi ti a ti bẹrẹsi sọ lati Satide ijẹjọ, bẹ a ko le sọ wipe nigbati a ti la gbogbo ọrọ na yekeyeke nisisiyi, nitorina awọn oyinbo ọlọkọ-ilẹ tabi Manager of the Railaway ni lati gba itọ wa dami, agbẹdọ! ohun ti a nfẹ ni wipe ki nwọn yọda fun awọn Imale ki nwọn le ma şe lo ọdun wọn nile lọjọ kan şoşo pere; ibanujẹ pataki lo jẹ fun ẹniti o yẹ wipe ki o şe ọdun ni ile rẹ, ti o si jẹ wipe ọran tulasi ka yandeo o lo gbe lọ si ibi işẹ.

Ẹ jọwọ ẹ gba ọrọ yi yẹwo ẹnyin Railway ki ẹ jẹ ki awọn Imale ti o nşişẹ fun nyin ni Iddo bẹrẹsi gba isimi ọjọ kan fun ọdun wọn gẹgẹbi atẹhinwa, bi ẹ ba le şe bẹ fun wọn yio dara pupọ.

## AWỌN ALU GBAGBA GBANJO.

Iṣẹ ti awọn Onigbanjo (*Auctioneer*) nṣe ko kere, o ni wahala pupọ ninu ẹlomiran le sọ wipe ṣe iba ki nwọn gbe agogo sode wipe awọn fẹ ta ọja ki nwọn si ma han bi irẹ bayi pe :- *Offer for this*, ni itumọ rẹ pe ki nwọn diyele ọja kan, ki ẹniti o si fẹ ra ọja si diye kan le e, ki nwọn si ma gbe kẹrẹkẹrẹ lọ si iye ti ẹniti o ni ọja na fẹ ki onigbanjo (*auctioneer*) si sọ wipe going ! going !! gone !! ki nwọn si yara bere orukọ ẹniti o ra ọja na, ki nwọn si yara gba owo ọja ti oluwarẹ ra lọwọ rẹ. ni wara-nṣeṣa ki nwọn bu omi ṣan an lọwọ, ki onigbanjo si kọ silẹ lati da sinu iwe nla *Sales-book*, eyiti ẹniti o ba fun wọn lọja ta yio fi ọwọ si nigba ti nwọn ba san owo fun awọn ọlọja ti nwọn yio si yọ owo iṣẹ ti wọn, nitorina ọrọ ti buṣe ko lọ bẹ arara, iṣẹ wọn ki iṣe ohun ti a le fi oju di.

Ẹniti o ba fẹ ṣiṣẹ Gbanjo tita, ki ṣe alugbagba gbanjo, oluwarẹ ni lati mu orukọ rẹ lọ si kotu, o si ni lati bura, lẹhinna o si ni lati ma sanwo fun awọn Munisiba lọdọdun, ki iyẹn duro bẹ.

Lẹhinna wayi o, iṣẹ wọn jẹ ọja ta ,ọja ko ta, owo alaru ni lati pe, eyiyi ni pe, nwọn ri ọja ta nwọn ko ri ọja ta, nwọn ni lati san owo fun awọn Munisisiba lọdun, lẹhinna ẹwẹ, ẹniti ko ni ṣọbu fun ararẹ, ni lati haya ṣọbu o si ni lati ma sanwo Ṣọbu loṣoṣu fun oniṣọbu ti nwọn haya, bibẹkọ ko i ti fẹ ṣiṣẹ gbanjo, nitori o ṣoro lati ko ẹru ọja ti nwọn ba fun wọn ta si ikorita mẹta, bi igbati awọn ẹlomiran nko ẹru ile wọn sode bi ẹbọ nigbati awọn Munisiba ba kan si wọn pe awọn fẹ fun omi ati epo oyinbo ati ohun ti npa kokoro omiran tabi Ekute, sile.

Lori gbogbo rẹ, nwọn ni lati gba akọwe ti yio ma ṣe iranlọwọ iṣẹ yi, nitori ajeje ọwọ kan kole gbe ẹru de ori, gbogbo iṣẹ lo ṣe ṣe amọja si nipa ni nawo, ṣugbọn iṣẹ ti gbanjo bẹ kọ, ile tabi ilẹ kan ni onigbanjo yio fẹ ẹ lọ ta ni igboro tabi ni idalẹ ni ko ni mu akọwe bọni tabi ki nwọn ta ọja ni ṣọbu, o sa ṣoro fun onigbanjo ti yio fi Olu (*Hammer*) lu ilẹ tan ti yio si tun ma ṣe wahala kirakita lati kọ ohun ti nwọn ba ta sinu iwe wọn.

Nipa eyi awa gba wipe iṣẹ pataki gan lẹru ni nwọn nṣe, nwọn si nnawo daradara si idi iṣẹ.

Nitotọ gbogbo iṣẹ lo ni wahala ati inawo tirẹ, eyiti a le sọ wipe wahala ati inawo miran ju ti awọn onigbanjo lọ lọpọlọpọ.

Ẹniti o nmu ọna ilu oyinbo pọn ti o lọ kọ iṣẹ *Lọya*, iṣẹ *Dokita*. iṣẹ *Wọnlẹwọnlẹ* ati awọn iṣẹ miran, tabi ti o kan wulẹ lọ kọ iwe lasan lai ni ero pe on yio fi ṣiṣẹ ti on ba de ile, owo tamtam ni oluwarẹ ni lati na, ṣugbọn iyatọ diẹdiẹ mbẹ ninu rẹ. Ni aseko iwe owo *currency* ti olukuluku nnawo ya bi o ti fẹ, a ri Lọya miran tabi awọn oniiṣẹ miran bi *Wọnlẹwọnlẹ* ati *Dokita* ti nwọn ni ọpọlọpọ akọwe lọdọ, Ṣugbọn loni nkọ agbara kaka ni ẹlomiran fi ni akọwe kan ṣoṣo pere lọdọ, bi ẹlomiran tilẹ fi agbadaju ko akọwe jọ si ọfisi, Akọwe ya gba, ati sanwo Akọwe lo ṣoro.

Ṣugbọn awọn onigbanjo bi nwọn fẹ bi nwọn kọ nwọn ni lati lọ sanwo si apo awọn Munisiba lọdun, awọn pẹlu ẹniti o nṣowo ọti lọgbọgba.

Awọn kan mbẹ lọtọ ti nwọn ngbe Tebulu *Table* si ẹgbẹ kan tabi ni kọro wuruwuru kan ti nwọn nsọ wipe awọn nta gbanjo, yala awọn onigbanjo pataki lo nyan wọn si ode gẹgẹbi aṣoju lati ma ta ọja, ti nwọn si fi ara wọn joye onigbanjo lotọ a ko mọ.

Ti nwọn ba gbe tebulu si ode, ẹlomiran yio ko aṣọ ataiye-baiye ti a ko gbọdọ wọ fun ẹniti o ku Bata ati awọn nkan miran pẹpẹ bi yeri Andawura, Ẹgba (*Bangle*) ati oruka, ẹwọn ati awọn nkan miran, nwọn a ni awọn patẹ ọja gbannjo.

Bi gbogbo ẹnikẹni ba si duro si igi imu wọn lati wo ohun ti nwọn nta ati lati ba wọn ra ọja, ti nwọn ba diyele ọja kan, nigbati ẹnikan ba yọwo rẹ si iyekan, bi oluwarẹ ba jaja fun wọn ni owo bi oluwarẹ ba si duro lati gba ohun ti o yọwo lati ra ti o si ti fun wọn ni owo agbalẹlẹ ọgafa ni awọn onigbanjo Alugbagba na si ma yara dalohun pe owo rẹ ko i pe, o tun ku iye kan, bi o ba si di akatakiti pe iye ti, ẹ dajale ọja tabi iye ti awọn yọwo rẹ si ni on ra, nitorina o ko ra mọ ki nwọn fun on ni owo on, nwọn a ake kọri pe awọn ko ni fun oluwarẹ lowo. ki oluwarẹ lọ pe ọlọba ti o ba ni wa. Ki ẹlomiran ṣe orire li nwọn ma fun ni owo rẹ pada bi o ba wu wọn nwọn a fi owo oluwarẹ gbagi, aiya ti oluwarẹ ba lọ wa iye ti nwọn ba sọ wipe o tun ku ti yoi fi kun u wa.

Ohun ti o ru wa loju ti a fẹ mọ nipe awọn onigbanjo pataki lo yan wọn sode lati ma ta irọ ọja bẹ fun awọn enia, ani awọn onigbanjo wọ lo yan awọn janduku enia bẹ lati ma padẹ mọ awọn enia lọwọ pe awọn nta gbanjo ?

Ati pẹlu awọn onigbanjo alugbagba na gba aṣẹ ki nwọn to ma patẹ gbanjo wọn sikorita-mẹta lai ki ṣe inu Ṣọbu, ti o ba si jẹ wipe omiran mbẹ ninu Ṣọbu, irufẹ ọja tulasi bẹ dara lati ma ta fun awọn enia ?

Bi ko ba jẹ wipe awọn onigbanjo pataki ti nwọn gba iwe-aṣẹ (*Lisence Auctioneer* )lọwọ Munisiba ti nwọn si bura ni Kotu ti nwọn si nsanwo sinu apo Munisiba lọdọdun lo yan awọn ọni amumada ti nwọn ni awọn nta *Gbanjo*, loju ti awa o dabi ẹnipe nwọn fẹ pa iṣẹ gbanjo loku fun awọn onigbanjo. Nitoripe ẹru le ma ba ọpọlọpọ enia nisisiyi lati ma yọju si Ṣọbu gbanjo bẹlẹnti ki a ni ki nwọn joye ṣọbọṣọla lati na ọja tabi lati ra ọja lọwọ wọn, papa awọn ero idalẹ ti nwọn

le ma ra ọja gbanjo ti nwọn ko si mọ oju onigbanjo yatọ si ra wọn.

Awọn ẹniti a ni nwọn nlu kere gbanjo lode ti nwọn si nṣe gẹgẹbi a ti sọfun ni yi le ma pe ara wọn ni *Auctioneer* atata loju wọn bi bẹkọ, nwọn le jẹ onigbanjo pataki ni ilu, ṣugbọn irufẹ ọja tulasi ti omiran ninu wọn nta fun awọn enia ko dara to gẹgẹbi ilana ti a le sọ wipe o nbẹ o ninu iṣẹ gbanjo, a ko si fẹ ki nwọn ko okuta ba iṣẹ gbanjo, nitori ki awọn ẹniti o mọ dajudaju pe onigbanjo pataki ni wọn ni ilu le ma ri ọja ta daradara.

O ṣoro fun ẹniti o sọ wipe on fẹ ra ọja ni iye kan loni ti si ra ọja tulasi tabi ọja ipa eyiti o mu akatakiti dani lati tun sọ lọjọ keji pe ẹ ya a go onile yi kini ẹ nta, eyiyi nipe ki o tun sọ wipe on yio ya wo ohun ti nwọn nta, ambọsibọsi ki a ni ti oluwarẹ wa na ọja kan lati ra.

Ki iṣe wipe gbogbo awọn ẹniti o nduro ti onigbanjo nigbati nwọn ba fẹ ta ọja li awọn onigbanjo kọwe pe e, lati wa ra ọja; ṣugbọn nigba ti onigbanjo ba ti gbe kere agogo gbanjo sode, o pe gbogbo enia ni yẹn, taja-tẹran lo si ni lati de ibẹ, ẹlomiran le ba ṣọbọṣọla ati atojubọ de ibẹ, ẹlomiran ẹwẹ si le ba aniyan lati ra ọja duro ti ohun ti nwọn nfẹ ta, nipa eyi ko ni ki a fi agbara ati ipa ta ọja fun wọn, Onigbanjo ti o ba daniyan bẹ, on papa mọ wipe ọmọ ti ẹsẹ rẹ yio wọ ilẹ kurukuru lo nfẹ pọn on; abọ ọrọ to fun nyin.

## JIMỌ TO NKẸ RIRI TO NKẸ.

Ọjọ Jimọ ijẹsan ti o nṣe ọgbọn ọjọ oṣu March to pari yi ni awọn Musulumi wa kirun Jimọ ọdun gẹbẹbi iṣe wọn.

Ohun ti o mu wa fẹ rohin Jimọ ọdun wọn lọtẹ yi ni pe, Jimọ na kẹ riri ati pẹlu kẹ o si jẹ Jimọ oloyin, nitori pe ọjọ Jimọ ni nwọn kirun yidi, ki Ọlọrun ṣe ni Jimọ anfani ati ọdun ijo ati ayọ fun ilu wa. Amin.

Awọn Musulumi gbogbo lo peju si Jimọ na a fi Sọnni Shitta (Ṣẹriki Musulumi) ati Abibu Oki (Balogun-ilu) ti a gbọ wipe laluri ko jẹ ki nwọn le lọ, ki Ọlọrun fi aiya ile balẹ fun wọn ki o si ṣe ajinde-ara fun olukuluku won, Amin.

Olukuluku won lo ṣe ẹyẹ lọjọ yi, nwọn si wọ aṣọ ti o yẹ olukuluku bi aṣọ Aran, aṣọ Ṣẹda ati awọn aṣọ meremere bẹ, opopo Victoria ko ni alafo ni gbogbo igba ti nwọn fi tuka nibẹ, gbogbo ilu ndun yungba bi oyin Lemọmu Ligali papa dabi Woli Ọlọrun kan nigbati nwọn gbe ọpa—ẹsin (Khutubah) si iwaju rẹ, ti o si nfi ibalẹ ọkan yọ ẹsẹ lọkankan bi ẹsẹ ẹiyẹ olongo nigbati nwọn sin lọ si ile rẹ.

Ọkan Lemọmu yi balẹ ni apẹrẹ pe Ọlọrun Ọba lo yan on ni Aṣaju ilu, lọjọ kọkanla oṣu November 1923, lẹhin iku Lemọmu Buraimah lọjọ kejidinlogun oṣu October ọdun 1923 kanna, ọkan rẹ si balẹ sọdọ Ijọba Igẹsi pẹlu pe yiyan on si Lemọmu yi ko ṣẹhin wọn, ko fi ọtẹ ṣiṣe joye, bẹ ni oye na ko si jẹ logun eyiyi ni pe ogun baba rẹ ni, nitoripe baba rẹ Nọlla ni awọn Musulumi-ilu fi jẹ oye Aṣaju wọn, ninu ọdun 1882 ki o to papoda lọdun 1890, ki Lemọmu Buraimah ologbe to tẹwọ gba ninu ọdun 1890 kanna di ọdun 1923, eyi ti a le ṣiro si ọdun mẹtale-logbọn si ra wọn.

A tọrọ ẹmi gigun ati ilera fun Lemọmu Ligali ki Ọlọrun jẹ ki oye na le mọ lori kalẹ, ki o si da awọn ẹmẹwa rẹ si fun u—Amin fatiha.

## AWỌN MUSULUMI ATI OYINBO AṢOJU-ILU.

Lọjọ Jimọ ọjọ 30 oṣu March ti o kọja, awọn Musulumi Eko ni (*Centre Mosque*) lọ si ọdọ Oyinbo (*Asoju-ilu*) Birrell-Gray ni ibi iṣẹ rẹ.

Awọn ẹni bi Alaji Sọnni Giwa, Alaji Mustafa, Alaji Abudu Davies, Kasunmu Gabjabiamila (*Bashorun*) Seidu Tẹlla Abudu Raimọnu Adamu Animashawun Sule Arowoṣesuna Aboo Bakare, Lawani Aguda, Badiru Abina, Aminu Idi Abudu Ramọnu Aranmọletiọṣọ ati awọn jakanjakan.

Nigbati nwọn de ọhun nwọn fi aye ibiti nwọn yio joko si han wọn. Nigbati ẹsẹ pe tan, bẹni Oyinbo Aṣoju-ilu de, gbogbo wọn si dide ki pe *Good-Afternoon* on na si fi tẹrin-tẹyẹ da wọn lohun, gbogbo wọn joko.

Aṣoju-ilu:—On gbọ wipe ẹ mbọ wa si ọdọ on lati ọdọ Alufa Adamu Animashawun.

Alaji Sonni Giwa:—Bẹni.

Aṣoju-ilu:—Ẹ wa ba on sọrọ ni, tabi ẹ wa ki on fun ti ọdun.

Alaji Sonni Giwa:—A ko ba ti ọrọ wa a wa ki ọ fun ti ọdun ni.

Aṣoju-ilu:—Inu mi dun lati ri nyin loni ati pẹlu nigbati mo gbọ wipe ẹ mbọ wa si ọdọ mi, mo ṣebi iba awọn enia diẹ bi mẹrin tabi mẹfa lo mbọ nko mọ wipe ọpọ enia bayi lo mbọ wa si ọdọ mi, nitorina mo dupẹ fun nyin gidigidi fun irufẹ ọna jinjin bayi ti ẹ ti wa ki mi, ati pẹlu mo ti ri nyin o pẹ diẹ, nigbana li a fi mbẹ leti P. W. D., ri ibiti a ti fi ṣe ile-iṣẹ (Office) wa ri nitorina, mo ki nyin fun ti ọdun ti ẹ ṣe, lẹhin ti ẹ ti gba awẹ pari, Ọlọrun ko fi ọpọlọpọ han wa.

Ohun ti mo fẹ sọ ni wipe emi ni Aṣoju ilẹ yi loni, ẹni keji mi ti o joko yi si ni igbakeji mi, mo nfẹ ki ndabi baba fun nyin, gẹgẹ bi Ijọba ti yan mi gẹgẹbi Aṣoju ilu, ohun ti ẹ ba si ri ti ko ba ye nyin to, ẹ de ọdọ mi, nko si fẹ ki ẹ ma jinna simi tobẹ, ni iwọn igbati ẹ ba si fẹ ri mi ki ẹ ma jẹki ntete ma mọ tẹlẹ, ki nba le ma mura silẹ de nyin.

Alaji Sonni Giwa:—A gbọ gbogbo ohun ti o ba wa sọ, awa na fẹ lati ṣe bi ọmọ fun ọ, a si fẹ ki a ma de ọdọ rẹ lẹkankan, a si fẹ ki iwọ na ma ṣe bi baba fun wa, nigbakugba eyi owu ti a ba nwa si

ọdọ rẹ, ṣugbọn nisisiyi awa jẹ aguntan, iwọ jẹ ẹkun bẹ ọdọ ẹkun rẹ kẹ, o ṣoro yọju si, nitorina ni ko jẹki a le ma de ọdọ rẹ nigbakugba tabi ti o ti mu wa de ọdọ rẹ lati ọjọ gigun diẹ sẹhin, ti o ba si nfẹ wa nitotọ o ni lati ma bere awọn nigbakugba.

Aṣoju-ilu:—Bẹni gẹgẹbi ẹ ti pe mi ni ẹkun, mo fẹ ki ẹ mọ wipe ẹkun ṣoro wọ ilu, eyiti ẹ si sọ wipe nko mbere nyin tabi on ko wa nyin lati ri, o ṣoro fun mi lati ma ya oju ile nyin ati pẹlu bawo ni mo tiṣe le mọ ibiti gbogbo ẹnyin ti ẹ wa nibi yi gbe ngbe tan.

Nko fẹ kiẹ wọn lọdọ mi arara ati pẹlu ki o to to ọdun miran, ile-iṣẹ awọn yio ti bọ si itosi eyiyi ni *Broad Street*.

Alaji Sọnni Giwa:—Ndara, awa yio ma jẹki o ri wa, aseko ti a ba si nfẹ wa ao ma jẹki o gbọ tẹlẹ.

Aṣoju-ilu:—Ogbẹni Tubi lọ gbe ohun alejo wa.

Ọgbẹni Tubi:—O gbe igba (Calabash) nla kan ti nwọn ṣe ọna si, eyiti obi (Kolarnut) Gbanja mbẹ ninu rẹ wa si ori Tebulu niwaju oyinbo Aṣoju-ilu.

Aṣoju-ilu; mu obi mẹta ninu obi na, o la si ọna mẹfa, o npin alawẹ rẹ le awọn agbagba ti o mbẹ ni iwaju rẹ lọwọ, o si ni ki nwọn ma gbe lọ ohun alejo nyin ni iyẹn o, o nlọ o digbo ọ ṣe o! Gbogbo wọn si dide nwọn ngbọwọ lọwọ rẹ karikari.

Inu rẹ dun pupọ lọjọ yi lati ri awọn Jamat Musulumi—ilu lọdọ rẹ inu awọn "Ilu" papa si dun lati yọ mọ daradara, gẹgẹbi Alejo ti o ṣẹṣẹ de si arin ilẹ yi, bi sisunmọ ti nwọn ti sunmọ bayi lati bi ọdun mẹta lo mu wa a ko mọ.

Jamat-ilu ati oyinbo Aṣoju-ilu, nipa ẹwọ jijẹ, a fẹ ki o ba wa gba awẹ diẹ lọdun to mbọ, Aṣoju-ilu ni o dara on yio gbidanwo, ki Ọlọrun ṣọ wa di igba na, olukuluku tuka. Awọn ilu si mbọ wa'le pẹlu ilu (Drums) larin iyi ati ẹyẹ.

### Ẹ BA TETE FI EPO OKO JAGA.

A gbọ wipe awọn Onilu ti lọ d aawọn obinrin to npatẹ Aṣọ oke ati Ilẹkẹ ni Scott Street ni kọro ile Ologbe Burrel Vaughan riboribo ni Satide to kọja pe ki nwọn lọ mu Ibusọ si Oke-Arin. A koi ti gbọ bi awọn Alatẹ wọnyi yio ṣe gẹgẹbi ifẹ awọn Munisiba, ṣugbọn ohun ti a fẹ julọ ni pe ki nwọn tokere fi epo oko jaga.

### Ẹ KU IPAMỌ EASTER.

A ba gbogbo olukuluku nyin yọ fun ọdun Easter (Ọjọ Ajinde Kristi) lọla Sunday, ọpọlọpọ enia lo ti ni tanma pe on yio ba wọn ṣe Easter lọdun yi, ti nwọn si ti fi ilẹ bora loni ki Ọlọrun fi iṣẹ Rẹ ṣọ wa o.

Emi ni tiyin nitotọ,

KEKERE AWO.

## ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ

*(Translated from "Character by Dr. Smiles")*

APA KẸTA.

Eyi ti o fẹrẹ jọ eyiti a sọ yi, ti a gbọ ni ti Dr. Paley. Ni Christ College, Cambridge nibi o nkọ ẹkọ, nwọn mọ pe omu ni ati pe enia kan ti ko yayi ni, ṣugbọn awọn ẹgbẹ rẹ fẹran rẹ, nwọn a si ma fi ṣẹfẹ. Bi o ti jẹ ẹniti ori rẹ ji si iwe to ni, sibẹ o jẹ ẹnikan ti ko ni irori, o ya ọlẹ. o si ya apa; titi o fi ṣe ọdun meji gbako ti o si bẹrẹ ẹkẹta ni College, ko ṣe iṣẹ ti o dara nkan kan. Lẹhin ti o ti wọ ode oru, lọ nijọkan bi iti ma ṣe, ti o pada sile, ọrẹ rẹ kan tọ wa ni owurọ nibiti o wa na gbalaja silẹ. O ni, "Paley, mo sun ti, tirẹ ni mo nro. Mo nsọ ni ọkan mi pe, aṣiwere irufẹ ewo ni ọ! bi mo fẹ, emi le wọ ode oru, owo ti nma fi ṣe wa ni ọwọ mi, bi o ti wu mi, mo le ṣai ṣe iṣẹ: talaka ni ọ, iwọ ko ni ipa rẹ. Ki a tilẹ ni mo gbidanwo, ko daju pe emi le ṣe iṣẹ kan: ni tirẹ ko si iṣẹ ti o ko le ṣe bi o ba fẹ. Emi ko sun titi ilẹ fi mọ ti mo nro ti iwa aṣiwere ti o nhu; mo to wa nisisinyi lati wa ki ọ ni ilọ. Ṣugbọn ti o ko ba gbọ, ti o ko ba ṣiwọ, emi ko ni ba ọ ṣe pọ mọ lai!"

A gbọ pe ibawi yi wọ Paley lọkan tobẹ ti o fi yipada lati ọjọ na.

Ọna miran pata-pata gba ni o wa mu tọ, o si fi ori ti i.

O wa di ọkan ninu awọn ọmọ ile-iwe ti o nṣe iṣẹ bi gidigidi ọkan'kan ni o nya awọn ẹgbẹ rẹ ti o nba fi silẹ. nigbati ọdun na si pari ti nwọn ṣe idanwo on ni o jẹ ori gbogbo wọn ninu ẹkọ iṣiro (*Senior Wrangler*) Gbogbo wa ni o si mọ iru iṣẹ ti o wa ṣe lẹhin na gẹgẹ bi Okọwe ati Onişẹ-Ọlọrun.

Ko si ẹnikan ti o mọ riri iru agbara ti apẹrẹ ẹlomiran ni lori awọn ọdọ ju Dr. Arnold lọ. Eyi ni pataki ọna ti o nlo lati kọ awọn ọmọ ile-iwe rẹ ni iwa rere. Iṣẹ pataki ti o kọju mọ ni pe nipa apẹrẹ iwa rere on papa, o mu ki awọn ọmọ ti o jẹ aṣiwaju ma hu iwa rere si awọn ẹlomiran, o si tun mu ki awọn iyoku nipa fifi-ara we, nipa titẹ-le apẹrẹ ati nipa gbigba fun awọn ti o jẹ aṣiwaju wọn, ma hu iwa rere bakana. O gbidanwo lati mu gbogbo wọn ni ọkan pe, on pẹlu wọn ni o njumọ ṣe iṣẹ pọ, ati pe on pẹlu wọn ni o ni lati ni iwa rere fun ire ile-iwe na. Ere kini ti o ti idi ọna ẹto rere yi yọ ni pe, eyi mu ki awọn ọmọ ile-iwe na ni iwa. Nwọn mọ pe oluko wọn fi ọkan tan wọn. Ṣugbọn a ko fẹ awọn ọmọ buburu ku ni "Rugby, bakana bi ti awọn ile-iwe miran; awọn wọnyi ni oluko wọn ko fi oju balẹ fun ki nwọn ma ba ba awọn iyoku jẹ. Ni ọjọ kan o pe oluko kan ti o wa labẹ rẹ, o ni: "Iwọ

ko ri awọn ọmọde meji ti o nrin pọ ni? Emi ko ri won pọ ri. Mo fẹ ki o ṣe ayan lati wadi irufẹ ẹgbẹ ti nwọn nko, tabi awọn ti nwọn nba rin: ko si ọna miran ju eyi lọ ti a fi imọ eredi iyipada ninu iwa ọmọde."

Apẹrẹ iwa Dr. Arnold, gẹgẹ bi ti gbogbo awọn awọn olukoni rere miran, jẹ eyiti o mu awọn ẹlomiran huwa. O mu ki awọn ọdọmọkunrin kọ lati mọ iwọn ara wọn, eyi si mu wọn ni iwa rere. Opitan rẹ sọ pe, "O dabi ẹnipe ti nwọn ba ti ri i, nwọn a ni okun eyi a si mu wọn mura si iṣẹ, a mu wọn lọ siwaju titi lọ lẹhin ti nwọn ti kuro lọdọ rẹ; a si dabi ẹnipe kọ fi wọn silẹ lọsẹ kan, tobẹ ti nigbati iku mu lọ, o dabi ẹnipe oya ko ya wọn nigbati nwọn nro ti iṣẹ rẹ ati ti isọkan-pọ awọn pẹlu rẹ eyiti ko le parẹ lai."

Bẹni a ri pe Dr: Arnold kọ ogunlọgọ awọn ẹnirere ati ọmoluwabi, awọn ẹniti o si ntan apẹrẹ iwa rẹ ka gbogbo aiye.

Bakana ni a gbọ nipa Duga A. Stewart, pe o ni emi ifẹ iwa rere si inu gbogbo awọn ọmọ ile-iwe rẹ gba.

Ologbe Lord Cockburn sọ pe, "nigbati o ba akọ ni, loju mi a dabi ẹnipe ọrun ṣi silẹ. Emi a mọ ara mi ni enia. Nigbati o ba nfi oye ọrọ ye ni lọna ti o gba muṣe, a dabi ẹnipe mo wa ni aiye miran x x x awọn ọrọ rẹ mu mi yipada."

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## *IN MEMORIAM.*

In loving memory and affection remembrance of

J. EGERTON SHYNGLE, B.L., M.L.C.,
*(late Leader of the Nigerian Bar).*

who died at Lagos on the 19th March, 1928.

"The boast of heraldry, the pomp of power
And all that beauty all the wealth ere gave
Await alike the inevitable hour
The paths of Glory lead but to the grave."

AYODELE BRIGHT.

## NI IRANTI.

Ni iranti iya mi ọwọn
MADAM FABIYI ỌLỌTỌ

Ni ọjọ kẹfa oṣu April ti ọdun ni lo di ọdun mejila ti iya oninure yi lọ jẹ ipe Olodumare.

Apẹrẹ inu rere ati iwa rere si ẹbi, ọrẹ ati awọn ọmọ rẹ fi ara han ni ọjọ iku rẹ.

Gbogbo ibatan, ọmọ ati ọrẹ rogba yika lati ri opin rẹ.

Ki Baba maṣai f'ori jin. Amin.

J. KEHINDE ODUWOLE.

1, Apatira Street,
Lagos.


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hapun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, APRIL 7, 1928

## KRISTI AYỌRUNBỌ TUN JI DIDE, *ALLELUIAH !!!*

Lati kutukutu hai arọ ọla ni ariwo ayọ yio ti ma ta pe "O jinde" "O jinde"—Talo jinde? Kristi Atohunṣe lo jinde—Kristi Alagbala-jaiya-jaiya lo jinde, Kristi Afifẹ fanimọra lo jinde kuro ninu oku; ọjọ to tun ju ọjọ yi lọ fun gbogbo onigbagbọ di ṣaṣa, ayaṣebi ọjọ ibi rẹ; awọn onigbagbọ ko le ṣai yọ si irufẹ ọjọ ọla nitori o jẹ ọjọ ijẹri pataki pe Ọlọrun wa ki ṣe Ọlọrun awọn oku eyini ni pe otitọ ti Kristi ku fun si tun ji dide ni akọtun, eyi si fi han pe iku ko ri Kristi gbeṣe, nitori o ti pa kokoro iku jẹ nipa lilakaka rẹ lati mọ ijinlẹ ofin ẹmi; bayi ni ẹ o si ri pe ẹnikẹni ti o ba le ṣayan lati pa ofin ẹmi mọ yio lagbara lori iku. Ẹ ko ranti Woli Elijah? Ẹ ti gbagbe Enọki niyẹn? Enia bi awa ni awọn mejeji wọnyi jẹ ṣugbọn ẹ ko ri bi ekinni ti lọ s'oke ọrun l'aye ninu kẹkẹ ina, ti ekeji si ba Ọlọrun rin ti a ko si ri mọ? Laisi ani-ani a ko ṣai mọ pe a pa awọn enia mejeji wọnyi larada, ki nwọn to jogun ile aiyeraiye ni ti t'emi t'ire njijadu si kita lati wọ inu rẹ lọ nisisiyi; irufẹ Ajinde Kristi ti a o ke ibosi rẹ lọla, ki iṣe Ajinde ti ara iku yi, ara eru fun eru, erupẹ fun erupẹ, ekuru fun ekuru, bikoṣe Ajinde ti ẹmi. Boya a le ri awọn ẹlomiran ti yio ma jiyan pe "bi o ba ṣe ara ẹmi ni Jesu gbewọ nigbati Maria Magalane fi ri ninu ọgba ti a sin oku rẹ si, kini ṣe ti ara ẹmi na fi dabi ara iyara bẹ? Esi irufẹ ibere yi ni pe:—Sura ara-iyara ko yatọ si ara ẹmi, bikoṣepe ohun ti a fi ṣe ekinni, ekeji wọn lo yatọ. Ẹniti o ba ri Ejo bi o ti npofọ tabi Akan bi o ti npa'wọ rẹ da fun titun miran, yio ni oye ohun ti a nsọ yi.

Gidipā, a ṣebi St. Paul ti sọ fun ni pe—"ara-iyara mbẹ, ara ẹmi si mbẹ;" daju-daju ara ti Kristi gbewọ ni aya'jẹ ọla jẹ ara ẹmi, eyiti o fi goke re ọrun lẹhin ogoji ọjọ lẹhin Ajinde rẹ. Jesu ko le gbe ara erupẹ lọ si isalu ọrun, nitoripe "Ara ati ẹjẹ ki yio le jogun ijọba Ọlọrun, bẹni idibajẹ ki yio le jogun aidibajẹ"—iyẹn l'ọwọ kan.

Ofin ẹkọ nipa ti ẹmi jinlẹ gidigidi, ko si si eyiti Kristi ko mọ fau-fau ninu rẹ; aṣiṣe ti awọn ti nwọn ni ara-erupẹ ni Jesu gbewọ ni Ajinde rẹ ṣe ni pe ki iṣe ofin ẹda fun oku ti o ti ku ni iwọn ọjọ mẹta sẹhin ki o tun wa nẹgẹnẹgẹ, idibajẹ kekere ko le ṣai ma ṣe ati wọ ara oku na, ẹniti o ku ti lọ korofo rẹ lo ku; nito ina nigbati Ẹlẹgba jinde ni aya ọla„ara-ẹmi ni awọ rẹ fun apẹrẹ, bi oku kan ba ku nibi kan, ti o ba fẹ f'arahan ẹnikẹni lokere, ti oluwarẹ ko mọ pe o ti ku, ẹ o ri pe oluwarẹ yio ri Lamọrin n a gedegbe, gẹgẹbi ẹrupẹ ara-iyara lo wa, ṣugbọn ti oluwarẹ ba le ṣe ofintoto rẹ, lọgan ara na yio pōra mọ loju; njẹ nigbati oku fi ara han enia bayi, ara-iyara ha ni bi? O ti o, bikoṣe ara ẹmi; ni ọna yi ni ti Ajinde Jesu bọ si.

Bawo ni iba ti ri ti a ba le ba Kristi jinde ni aya ọla ki a si ji kuro ninu ōrun ẹṣẹ wa lọnakọna? O yẹ ki a yọ ayọ Ajinde yi gẹgẹbi ọmọluwabi, ki ṣe pẹln iru ọti pata, ija, asọ tabi ohun alebu miran, ti yio fi di ogun a nsọgọ ẹni gọgọ lọ si ibiti ko wọ. Alemu ko y'agba, k'agba ma ṣe ohun alemu !!!

Ẹwẹ, ohun ti o tun ku diẹ ki o to ni ti ọjọ Ajinde yi ni pe ko wa gẹgẹbi ọjọ Keresimesi ti gbogbo wa mọ ni ọjọ 25 oṣu *December* ọdọdun; pupọ ninu ẹnyin oka wa le ṣakiyesi nigba pupọ pe ọjọ ti awọn Alaṣẹ *Church* fi ọjọ Ajinde yi si ma nyi lagogo lọdọdun; lọdunni o bọ si ọjọ keji oṣu yi, lọdun to mbọ, o le bọ si oṣu *March* bayi ni a ti nba bọ fun ọjọ jọjọ. A rentisa kan pe Ọgbẹni Ọlọla kan ( *a noble Lord* ni ilu Oyinbo mu alamọri ohun ti a sọ yi wa siwaju awọn Ẹni Ọla Ajọ Igbimọ ti England ( *House of Lords* ) pe ki *Church* fi aṣẹ si ọjọ kan gbọn bi ọjọ *Easter* gẹgẹbi ọjọ Keresimesi gẹgẹbi a ti ri ka ninu ikan ninu Iwe irohin ilu na ti a npe ni *The Times* a sọ lu Ọlọla yi nigbana pe Ajọ Igbimọ yio fi imọran

rę s'ero gidigidi, nwọn yio si şe bi o ti tọ nipa rę nigbati o ba şe; şugbọn anu şe ni pe lati igbayi,—o nto ọdun kẹta nisisiyi—a ko gbọ pa, bẹni a ko gbọ mu u mọ; bi Aya (Inaki) kan ba kofiri rę, ęgbęrun wọn lo ri ọ yẹn, a sọ eyi fun ẹnyin Igbimọ *Church* ti o wa ni *Nigeria* patapata.

Njẹ ẹnyin ara, ẹ ku ewu Ajinde, Ajinde ara a ma jẹ fun olukuluku wa o, Amin; apa ekute ile ko ka'wusa, nibi yiyi kiri lo mọ. pa araiye ko ma ka t'olori t'elese wa o, Aṣọ—Ẹ ku ewu ọdun!!!

---

## IDAYI ANA, YEPARIPA! IDAYI ỌLA, *HALLELUIAH* !!

[ Wosika Lati ọwọ Atari Ajanaku ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Ti'bi-ti're ni ipin ọmọ enia li ode aiye; ibanujẹ ati inu-didun, wahala ati isimi, ẹkun on ayọ, iṣa ati iyọ, gbogbo wọn li o nṣe iṣẹ po fun rere Bi Yeparipa ti jẹ aro ikanu, bẹni *Halleluiah* je ihó ayo. Bi ẹkun pẹ di alẹ kan, kiyesi, ayọ nbọ li owurọ.

O nlọ si ẹgba ọdun nisisiyi, ti a bi Jesu si Bethlehem ilẹ Judea, ni ibujẹ ẹran. L'aisi ani-ani, Mary afẹsọna aya Joseph ni Iya rẹ, Bibeli si kọ ni wipe, Ẹmi Mimọ ni a fi l'oyun rẹ; Alukurani si jẹri si eyi wipe, Maleka Jibrilla ni Ọlọrun ni ki o fẹ atẹgun si Moriamọ li aṣọ ki o to l'oyun Anọbi Isa.

Li akoko ti Joseph nkọ iṣẹ gbẹnagbẹna tabi Kapinta lọdọ Ọgbẹni kan ti a npe ni Naason, boya Mary nigbana nrọ ojo l'ọrun; ṣugbọn lẹhin ti Joseph kọ iṣẹ tan, ti o si ṣi Ṣabu gbẹnagbẹna fun ara rẹ ni a gbọ wipe o bẹrẹ si fẹ Mary ni afẹsọna. Yala o ti fẹ obinrin miran ṣiwaju Mary tabi ko fẹ ni o, Bibeli ko sọ fun ni, bi a ko si ti le sọ, ẹwẹ, wipe Mary tun bi ọmọ miran le Jesu tabi ko bi, a ri i ka wipe, li akoko kan ti Jesu nkọni ni Tẹmpili, awọn agbalagba ti o wa nibẹ nbi ara wọn lere wipe "Eyi ha kọ ni Jesu ọmọ Mary ti a mọ arakunrin rẹ, James Joses, Simoni, Juda ati awọn arabinrin rẹ (*Brothers and Sisters*) bi ẹni mọ owo?

Eyi jẹ ki a ro wipe boya Joseph ti ni aya ri, ati wipe Iyale rẹ yi si ti bi ọmọ mẹrin tabi marun fun u ki o to fẹ Mary Iya Jesu; bi bẹkọ, ẹ o gbọ li ẹnu awọn Alufa ni Ṣọṣi ọla tabi ti ọsẹ ti o nbọ—ṣugbọn a ko le fẹ iwe ti o sọ nipasẹ ile ati ọna Joseph gbẹnagbẹna ju eyiti Bibeli papa sọ nipa rẹ lọ kù lọwọ wa o.

Nigbati Jesu dagba diẹ, o bẹrẹ si kọ iṣẹ Kapinta li ọdọ Joseph ọkọ Mary Iya rẹ, lati kekere ni a si ti gbọ wipe o nṣe ohun abami oriṣiriṣi, okiki rẹ bẹrẹ si kan kiri agbegbe ilu ti o wa, ogunlọgọ enia li o si nja ijakadi lati mọ ọ.

Nigbati o di ẹni ọgbọn ọdun li o wa bẹrẹ iṣẹ iyanu tarata—iṣẹ iyanu bi lila oju afọju, mimu amukun lara da, Bibeli si sọ fun wa wipe, O tilẹ nji oku dide.

Mejila ni ọmọ rẹ, o si nkọni nigbagbogbo ni Tẹmpili, Sinagogu ati ibomiran pẹlu. Oruko Jesu di ẹru jẹjẹ fun awọn Farisi, awọn Amofin ati awọn alagabagebe. Okiki Jesu ngbilẹ—awọn enia si ndi rikiṣi ati tẹmbẹlẹkun si i.

Iyoku di iregbe, a gbọ wipe ọkan ninu awọn Ọmọ-ẹhin rẹ mejila gba ibọdi, o si fi ifẹnukonu (*Kissing*) fi Jesu han awọn ọlọpa ti o mu u nitori ẹsun ti nwọn fi sun u wipe, O pe ara rẹ ni Ọba awọn Jew, ati wipe, O si nṣe ohun ti o lodi si ofin Kesari, Ọba ilu.

A mọ wipe bi Judasi ko tilẹ gba ọjẹgẹ ati fi Jesu han, ko si igbati ọwọ ọlọpa ko ni tẹ ẹ, nitori ki a tilẹ wipe nwọn ko mọ Jesu papa li ojukoju li arin awọn Ọmọ-ẹhin rẹ, ti ọlọpa ba mu gbogbo awọn mẹtẹtala pọ pẹlu Jesu, ti olukuluku awọn Ọmọ-ẹhin mejila ba nsọ orukọ ara wọn tan, awọn ọlọpa Ọba ko ni ṣai mọ wipe Jesu ni ẹnikẹtala ti o ku.

Ṣugbọn sibẹsibẹ, iwa buruku ni Judasi hu; iwa apania, iwa amọni ṣeni.

Onigbagbọ wo ni ko ha korira Judasi pupọ nitori eyi? Bẹni iwa ọpọlọpọ Onigbagbọ, iwa ọpọlọpọ Alufa wọn miran pẹlu li o buru pupọ ju ti Judasi lọ.

Iwa amọniṣeni, iwa ekute bunijẹ fẹni, iwa apani-ma-yọ-da. Ngbo? Ọlọrun nikan ko lo mọ iye igbati ẹ ti nyọ kẹlẹkẹlẹ lọ si ile oniṣegun lati ṣe ọmọ ẹnikeji nyin ni ṣuta. On nikan ko lo mọ iye igbati ti ẹ lo purọ mọ ẹnikeji nyin lọdọ ọlọpa inu ati ọlọpa ode ti nwọn si ju s'ẹwọn nidi ọran ti ko mọwọ, ti ko mẹsẹ?

Melo la ha le ka ninu awọn ẹniti araiye ti fi wahala, irẹjẹ ati ibanujẹ ran lọ si ọrun apapa-adodo. Judasi! Judasi!! kini Judasi ṣe ti ẹnyin ko ṣe ri, tabi kini Judasi ṣe ti ẹnyin na ko le ṣe? Olotitọ Ilu ni ika Ilu—O nṣe ki-ki ninu nyin.

Nigbati Jesu ngun kẹtẹkẹtẹ lọ si Jerusalem,, igbe *Hosanah, Hosanah* ni a ngbọ lotun losi, ṣugbọn ni ijọ kẹfa pere lẹhin na, igbe *crucify him crucify him*, kan mọ agbelebu, kan mọ agbelebu, ni a tun ngbọ lẹnu tọmọde t'agba. Ẹnu wọn l'ọfa, ẹnu wọn l'oje.

Ninu Alukurani Suratun Nisa ori kẹrin ẹsẹ karun di ati ikẹrin di logojọ a ri ka nibẹ pe Jesu ko ku lori agbelebu, ati pe o fi ẹlomiran parọ ara rẹ. Ọlọrun si mu u lọ soke ọrun lalye, ṣugbọn

Bibeli sọ fun wa pe Kristi ku iku oro lori agbelebu nitori wa, o si jinde kuro ninu oku nijọ kẹta—*Alleluiah.*

Tani Jesu ku fun? Anu ṣe wa pupọ lati s'akiyesi pe ọpọlọpọ Ṣọṣi isisiyi lo nhuwa bi ẹnipe nitori awọn Alarede (*Monogamists*) ati awọn ọmọ wọn nikanṣoṣo ni Jesu ṣe wa si aiye lati fi ara rẹ rubọ, ati pe nitorina gbogbo ẹnikẹni to ba fẹ ju obinrin kanṣoṣo lọ (*Polygamists*) pẹlu gbogbo ọmọ wọn ati aya wọn ni Esu ma fi tẹlẹ ina ọrun apadi, boya nitori Eṣu papa ko ni aya rara ni, owu jijẹ (*jealousy*) si jẹ ki o korira awọn obinrin pupọ, awa ko mọ.

Ṣugbọn awa mọ pe ti o ba jẹ nitori awọn olobinrinkan-ṣoṣo pere ni Jesu ṣe ku ni, ati nitori awọn ọmọ alarede njẹ asan ni igbagbọ ọpọlọpọ enia l'aiye, asan si ni idawo wọn si Ṣọṣi ọjọjọ isinmi. Ani to ba jẹ ẹniti olobinrin kanṣoṣo pere ti ko si ṣe "oju kokoro" si aya ẹlomiran rara ni ikọkọ nikan lo ma de Ijọba ọrun ni, nibo ni *Bishops Archdeacons Priests, Deacons* Iriju Ijọ, *Members Parochial Committee, Leaders*, ati *Sides members* miran l'aiye yio fi oju pamọ si lọjọ idajọ niwaju Ọba arinu-rode Olumọ ọkan.

*Christ Church Pro-Cathedral* le gba ọrẹ ẹgbẹrun pọnun (£1,000) lọwọ ẹniti o ni obinrin pupọ, *St Paul's Breadfruit Church* le tan ina *Electric Lights* ti ẹniti o ni obinrin pupọ ra si Ṣọṣi ibẹ, *St. Jude's Church* Ebute Metta le gba ẹbun ọgọrun pọun lọwọ ẹni ti o ni obinrin pupọ nwọn si le fi panu (*Corrugated Iron Sheets*) ti ẹniti o ni obinrin pupọ ra bọ orule Ṣọṣi wọn, ẹniti o ni obinrin pupọ le la'wọ si Ṣọṣi Arọloya, le la'wọ si Ṣọṣi Oke-popo, le ra wala ofin mẹwa si Ṣọṣi Olowogbowo ati ohun ẹyẹ miran ti a kọ *Glory be to God in the Highest and on earth peace and good will toward men* si, iru eyiti ologbe Ben Dawodu ra sibẹ. Ẹniti o ni obinrin pupọ le ṣe gbogbo nkan wọnyi ati jubẹ lọ, ṣugbọn ko gbọdọ daba ati sami (*baptize*) ọmọ rẹ!!!

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

**OLUSAKIN'S COLUMN.**

---

**Hardings—Wills—Jones. etc.**

As some funny wills made in this country may be mentioned the wills of the late Tom Jones and W. R. Harding. Funny in that they contain little or no provision for those who, under ordinary circumstances, were entitled to a lion share of the asset involved, but in respect of which the Testators who were the best judges thought otherwise. Worse things do happen in England as the following extract culled from an English newspaper indicates :—

**"One shilling to buy a Rope."**

HUSBAND'S BEQUEST TO HIS WIFE.

The Will has just been proved of a testator living at St. Leonards, and formerly of Bristol, who died on November 15th last. This will was written thoughout in his own hand and dated from Bristol on March 4th, 1917. In this he states "I give to my wife the sum of one shilling to enable her to buy a rope." He leaves a freehold house at Norwich to a St. Leonard's nurse, £10 each to two ladies living at Clifton Bristol and the residue of his property to his step sister, also living at Bristol. The value of the property is stated to be £437.

A similar Will was proved about 14 years ago, in which a man, living at Sulton Coldfield, near Birmingham left to his son 3½d with which to purchase "a hempen cord or halter for the use of his (son's) dear wife, which I trust she may make use of without delay." Wills of this kind are most often directed against matrimonial partners. Possibly the height of meanness was attained in this respect by a man who left to his wife the sum of one farthing, with the direction that the coin should be sent to her by post in an unstamped envelope. (This involved a charge to her of 8d., to delivery, being the charge for sending coin in an unregistered envelope and a further two pence for unpaid pastage). He justified his action by saying that she had spent much of her time in calling him "an old pig" and other names.

A member of the staff of one of our southern Railways who was well known to the travelling public, stated in his will :—My estate would have been considerably larger if it had not been for my unfortunate marriage with the cleverest known legal daylight robber. My associations with this perambulating human vinegar cruet I consider to have cost me considerably over £400."

**Mr. Oke Adeshigbin.**

Mr. Oke Adeshigbin who has been touring Oshogbo, Ilesha, and Ile Ifẹ on a trip, returned to Lagos on Thursday last the 29th ultimo. We say ẹ ku abọ.

**Engagement.**

The engagement of Miss Sally Aṣabi Byass, daughter of Mr. and Mrs. Byass of 10, Bishop Street Lagos with Mr James Dixon is announced to take place on Tuesday next, the 10th April, 1928.

**Birth.**

Madam Amdalatu Alhaji Isa, wife of Mr. Y. A. Adamson, of St. John Street, Lagos, of a baby boy, on Friday, the 30th March last. It is reported that both mother and child are doing well. Congrat.

**Archdeacon in Asylum.**

ECHO OF CHURCH SENSATION SEVEN YEARS AGO.

Central figure in a sensation of 1921, ex-Archdeacon John Wakeford, formerly Canon and Precentor of Lincoln Cathedral, Archdeacon of Stow, and Vicar of Kirkstead, has been removed from the hospital of Bromley Union to Barming Heath Asylum, near Maidstone. He had been at Bromley Union Hospital for a week, having been transferred there from his home at Biggin Hill, where Mrs. Wakeford now carry on business as a breeder of cats and dogs. On inquiry at Barming Heath Asylum, it was stated that the Archdeacon's condition was "restless and agitated," but it was hoped he would soon settle down in his new surroundings. Mr. Wakeford was first tried before a Consistory Court at Lincoln, in February, 1921, when he was accused of immorality. It was alleged that he had stayed with a young woman at the Bull Hotel, Peterborough, on two

occasions in March and April, 1920. This accusation was denied by Mr. Wakeford, and on being found guilty, he appealed to the Judicial Committee of the Privy Council. The decision again went against him, and he was deprived of all office in the Church. Incidentally, the identity of the young woman with whom, it was alleged, the Archdeacon associated, has never been established.

The ex-Archdeacon was recognised as one of the most eloquent and outspoken preachers in the Church. After holding various curacies in Devon, he was appointed to a Crown living in Liverpool, in 1893, by Mr. Gladstone. His progress was rapid, and apart from his success in the pulpit he was the author of some striking theological writings. Thoughout his trial there was great conflict of evidence and the Archdeacon contended it was all part of a conspiracy to hound him out of the Church.—*The News of the world*, 11/3/28.

### Congratulation.

We congratulate Master Gabriel A. Adeyeni, of the King's College, Lagos, son of the Oni of Ifẹ, who has recently passed the Junior Examination of the University of Cambridge.

To his brother and sister Prince Adeyemi and Princess Adelaju and to his guardian Mr D. A. Bright, ẹ ku ori re.

OLUSAKIN.

---

Ọgbẹni Olotu Eko Akete,

Mo bẹrẹ foji o.

Ni ọsẹ ti o koja lọhun ni mo bere ọrọ lọwọ The Igbajọ Union, wipe ṣe bi mo ri wọn ni Ile iṣẹ Oga awọn onilẹ ni o tun to kọja, ti mo si bi ẹniti mo ri na wipe kini wa ṣe ti o si wi fuu mi ohun ti on wa ṣe, ṣugbọn ti a ko gbọ ohunkohun nipa rẹ lati lati iye ijọ yi wa ma, eyi ti ati ilẹ mi si Ẹgbẹ na mu ki nbere lọwọ ni ọsẹ ti o kọja lọhun (*Saturday the 10th March*). Inu mi dun lati gbọ wipe ngo purọ lenu Akọwe agba Ẹgbẹ na B. S. Ọmọnijọ, ati wipe bi o ti da mi loju to tabi bi ngo ti purọ to, osi fi Ẹda iwe ti wọn ri gba lati ọwọ Ọga Olontẹ Ẹgbẹ (*Registrar of Company*). Ṣugbọn anu ṣe mi lati gbọ wipe owo koto lọwọ wọn, ati wipe awọn fẹ bi Igba panhun (£200) pẹlupẹlu Iwe adehun ko tilẹ ti dara to, Lori eyi emi ko fẹ sọro pipọ nitori wipe bi Iwe adehun koba dara to ti wọn bade ọdọ awọn Olotu Ofin, wọn atun eyini ṣe, ṣugbọn ki ni yio mu wọn de bẹ? Nitori wipe Ọkunrin fifun na wipe bi on ko basi ni Ile kẹ maṣe da imaran kan lẹhin on, owo apesẹnu womu. Lori eyi ni mo fẹ sọro si ni pataki. Mo mọ pipọ ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ yi ti wọn si jẹ ẹni pataki, lati ri igba panhun ni akoko yi on fẹ akiyesi, ati iṣe apa kitipi, bẹni a si lati ma gbọrọ won ni Ile Afari Ogun Lẹhingbẹti ati ni boran ni ile ere ni Ebute Mẹtta, B. S. Ọmọnijọ papa ti mọ wipe a ko le jokosi ojukan kama reti owo, pẹlu wahala ati iṣẹ ara ẹni lọpọlọpọ lohun fẹ, Ọgbẹni J. S. Ojo ko ṣai mọ eyi pẹlu "ṣe Joseph Lubọrọde, ati Adejokun kṣe Ọgbẹri, ẹtinlẹ ki ṣe ope bi ati ṣe wa owo sinu Ẹgbẹ, awọn Baba wa wipe "Owo oni ran afẹ ni ti ko si ṣẹ. Jọ S. A. Fabunmi so fun *the* Igbajọ *Union* ki o ṣe apa kiti po, ati wipe aki yio ṣe alai gba iya ẹgbẹ, Ajayi ati awọn ọmọ'gbẹ rẹ yaju pe ki wọn fun ọja wọn grigri.

B. S. Ọmọnijọ, wipe inu on yio dun bi ohun bale ri ẹni ti yio ran Ẹgbẹ on lọwọ iyekiye kan, atiṣe le ran Ẹgbẹ na lọwọ laijẹ wipe a mọ ohun ti Ẹgbẹ na fẹ ṣe, tabi kini ẹgbẹ na kojọ fun? '*It is good to know the object of* Igbajo *Union before one could know how to offer one's advice*) nitorina a bẹ B. S. Ọmọnijọ, ko jẹ ka mọ idi rẹ ti Ẹgbẹ fi nfẹ igba pọnun (200). Mo si tun ki nyin ẹ ku idele James Awope, ẹniti a gbọ wipe iya rẹ ku ni igboro Igbajọ ni ọsẹ tọhun (*week before the last*), ti awọn ọga rẹ fun ni aye lati lọ fi sinku iya rẹ, iya James Awope, Otunla, jẹ olowo nla ni igboro Igbajọ ni igba aiye rẹ, Otunla ọrun re o.

Baba Ẹgbẹ The Igbajọ Union, Bandele Jaiyẹọla, ẹ ku afẹku ẹgbọn nyin, Otunla, to ṣẹlẹ ni Igbajọ ni ọsẹ tọhun, Bankọle, ẹ ku ṣẹainde o, ẹ si tun ku idele Adeniyi. B. S. O, ẹ jẹki a mọ ohun ti Ẹgbẹ nyin wa fun o.

Emi niti nyin,
RIRO NITI ENIA ỌLỌRUN LOLUṢE.

---

Mr. J. S. Cleeg, First Class Clerk, Accounts Branch, Posts and Telegraph, proceeds on two months' vacation leave as from the 10th instant.

Leave will be spent at Abeokuta and Otta Districts.

---

## NOTICE.

### ISHOLARIAN CONGREGATION
OR
### THE NATIONAL CHURCH OF AFRICA.

### Anniversary Service.

In connection with the celebration of the 10th Anniversary of the above-named Church :—

A Special Thanksgiving Service will be held on Easter Sunday, April 8, 1928, in the same place, at 7 o'clock p.m. prompt.

Addresses by

DR. ADEDEJI ISHOLA, (D.M., D.D.)
*Olulana & Bishop Founder The National Church of Africa.*

Silver collection will be thankfully received in aid of The National Church of Africa.

All are cordially invited.

AMOS I. COLE,
*General Secretary.*

# Iyin Oluwa Medicine Store

**K. B. SAVAGE,**

*CHEMIST & DRUGGIST.*

STOCK :—

## YARO

***The oldest and best Infants Preservative 1/6d & 3/-.***

## WIRELESS FEMALE PILLS

***The scientific preparation for all monthly Disorders peculiar to Females. 4/6d per bottle.***

## KADUNA BALM

(IPARA AWO'GBA ARUN).

***Can be applied in 100 different ways !!! 1/-.***

## Write or call at :—

88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109, Griffith Street, Ebute-Metta.

**Watch this space every week.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*

*N B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

"Shake the Bottle."

### REMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nje pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s.) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ baje, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq. 41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

✓ A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi[illegible] ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa ritun to kọ[illegible] si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi ab[illegible] awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fu[illegible] ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.